IJỌ̀ ÒRÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́-ÌYANU

Olú Ilé-Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàíjíríà

ÀDÚRÀ SÓRÍ IYẸ̀PẸ̀ (APÁ KẸFÀ)

1. Ọlọ́run, dìde, lo iyẹ̀pẹ̀ yìí láti fidímúlẹ̀ sànmọ́nì àdúrà, ìwà-mímọ́, ìsọjí, ìwàláàyè Ọlọ́run yí wa ká, ní orúkọ Jésù.
2. Olúwa, pẹ̀lú ìyẹ̀pẹ̀ yìí, jẹ́ kí gbogbo ìmísí òkùnkùn tó n daàmú àláfíà agbègbè mi di lílé jáde nípa ìmọ́lẹ̀ Ọlọ́run, ní orúkọ Jésù.
3. Bí mo ṣe gbé ìyẹ̀pẹ̀ yìí dání gẹ́gẹ́ bí ọ̀nà ìbápàdé ti wòlíì, jẹ́ kí igbàgbọ́ mi gba okun si, jẹ́ kí a fi agbègbè mi jìn fún Ọlọ́run, kí a sì fi ìdílé mi múlẹ̀ nínú àláfíà, ní orúkọ Jésù.
4. Olúwa, lo ìyẹ̀pẹ̀ yìí láti fọ agbègbè mi mọ́ kúrò nínú gbogbo ìmísí tó n dènà àdúrà, ìwà-mímọ́ àti ìdàgbàsókè t'ẹ̀mí, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, pẹ̀lú ìyẹ̀pẹ̀ yìí, jẹ́ kí gbogbo sànmọ́nì ìdárungún sójúkan tó rọ̀gbà yí akitiyan mi l'ágbègbè mi gba ìrọ́pò nípa sànmọ́nì ìtẹ̀síwájú, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára tó n tako ìtẹ̀síwájú Ihìnrere l'áyiká mi, kí agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù borí rẹ, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, pẹ̀lú ìyẹ̀pẹ̀ yìí, jẹ́ kí gbogbo ibi gigia ìwà-ìkà tó n tako iṣẹ́ Ọlọ́run l'ágbègbè mi di fífà lulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
8. Bàbá, jẹ́ kí ìyẹ̀pẹ̀ yìí di ìyẹ̀pẹ̀ ogun jíjà, ìyẹ̀pẹ̀ iyàsímímọ́, ìṣẹ́gun agbègbè, ìmúpadà-bọ̀-sípò, ìsọjí, àláfíà, isèso àti ohun-ìní atòkèwá, ní orúkọ Jésù.
9. Bàbá, jẹ́ kí ìyẹ̀pẹ̀ yìí gbé ogun-jíjà lọ sí àgọ́ àwọn ọ̀tá mí, ní orúkọ Jésù.
10. Olúwa, jẹ́ kí ìyẹ̀pẹ̀ tí mo gbé dání lọ́wọ́ mi yìí gbé ìyàsímímọ́ agbègbè àti agbára iwẹ̀nùmọ́, ní orúkọ Jésù.
11. Olúwa, jẹ́ kí ìyẹ̀pẹ̀ tó mbẹ lọ́wọ́ mi yìí di ohun-ìjà ní àgọ́ àwọn ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.

12. Bí mo bá ṣe da ìyẹ̀pẹ̀ yìí sí agbègbè mi, jẹ́ kí gbogbo pẹ̀pẹ̀ ibi, májẹ̀mú ibi àti ìkórajọpọ̀ ibi tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ayànmọ́ mi yóò túká, ní orúkọ Jésù.
13. Olúwa, jẹ́ kí ìyẹ̀pẹ̀ yìí ṣàwárí gbogbo ọ̀tá ìtẹ̀síwájú ìkọ̀kọ̀ l'ágbègbè mi, kí ó sì rán idàrúdàpọ̀ sí àgọ́ wọn, ní orúkọ Jésù.
14. Bí mo bá ṣe da ìyẹ̀pẹ̀ yìí padà, jẹ́ kí gbogbo ṣẹ̀kẹ́-ṣẹ̀kẹ̀, ìdènà, ìdíwọ́, tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi fọ, kí ó sì parun, ní orúkọ Jésù.